# IROHIN LATI AGBEGBE

## IDAHUN ỌRỌ KANSELỌ J.O. ỌLỌWẸ
(Lati Ọwọ Kanselo J. O. George Ibodi).

Inu mi iba dun ti Olotu ba le gba mi laye lati fesi iba oro die fun Ogbeni Olowe lori oro ti won gbe jade ninu Iwe Irawo Obokun ti December 12 1955 to je ibanilоruko je ati ete ope patapata.

O je ijoju fun mi bi okan ninu omo ibile ati okan ninu olupeto ti gbimo ti akamo Ibodi yi pe Ogbeni Olowe le ba odinda igbimo kan loruko je wipe won je akamo igbimo awon wo lati gba owo ori.

Awon agba to mo epo lowe pe ogun ti ko ba kan ni ja ni arun ka to je. Bayin ko mo oro yin, Sugbon e si fesin mi e ni ibe na, ati pe eni ke oba niyanju ni boya yio sele.

Mo to wipe ki ee pe aye yen te e no ibe ni odun yi. E jowo nje e le se alaye ni yoki odun ti e ti agba owo ori Aye to to dupe ijoba pin akamo kokan si igbimo kokan-gburo wa.

Nitoripe ileto to ba ti nba ni se po tele ni won pin mo akamo olakuluku.

Iba ibiti enyin ati Ogbeni Ojongbede ti nfa tele yen ni eba je ko ko kusi ti iba dara bi ko basi ti owe ti awon agba ma npa pe okun ti agba ba ko se ni omode tiko le ni, aba mo ohun ti aba se fun tawa lori gbolohun kan pe "akowe Ibodi ati Akoda wa wa gba owo ori aye eyiti ki se eto won."

E jowo, e tun polowo e'eyi pe e ko wi be, nitoripe enun ti e nfi kan Igbimo yi yen doti re pupo. Iba to ba to tunu ohun ta nfi re, a ni eto re ti kato se.

E jowo e se atunse won yen kiakia toripe arin omo iya meji ko gba ija o. Ore ni a nni kun oro a ki ni ota kun ota.

A dupe Olotu. E o tun ma

## ṢE BI O TI MỌ
(Lati Ọwọ Oluṣola Agbesanya Ile – Oluji).

Olotu, mo dupe fun aye ti e gba mi lati so iba oro mi yi si inu iwe irohin yin.

Se bi o ti mo, oro yi ba awa odomokunrin wi pupopupo. Nipa okanjuwa kiko obinrin jo. Eniti ko ti to lati ni iyawo kan, yio ma ranse si Deneu, yio si tun ma ran ni si Emily. On papa yio lo ma se abuja Raliatu, nipa wipe ki won se iyawo on.

Nigbati okan ninu won ba ti le sope "Buroda, mo nireti pe oro na yio bon," ti awon yoku ba ti jaja lo gbo pe okan ninu won ti gba bo o, gbogbo nwon patapata a gba bo o bakanna.

Eniti ko se boti mo yio ma sope awon agba a ma pa owe bayi pe "alaju atimu koto nkan ti a ogbe sare."

Nigbati o ba jaja le ri owo ibasoro san o di wipe ki o ma yan ka igboro pe awon lo wa nibe.

Buroda, ma tun sope enyin lowa nibe mo, ki senyin lowa nibe. O ti gbagbe owo epo ni? ati owo iru? eran, eja nko? tabi eran namo ni Obirin koni ri owo ra loja ti gidigbo ko ni sele ni abo oja? Obirin ko, kama ri.

Li akotan are. E je ki a lowo moto, ki a si tun ni owo epo pelu. Igba yen ni oko sese to ra o.

O digba die na.

## MO BẸ ILE ITẸWE IJẸṢA WO
(Lati Ọwọ Ọmọba Gbadebọ Bẹpo, Abẹokuta).

Akindele Ojo, mo ki o fun oyaya ati ife re si orile ede wa ti a bi o ati si emi na lojo na lohun ti mo wa se ibewo ibi ile ise re.

Nitoto opolopo awon obirin loni iwa rere ni gbon iwo ta won yo, iwa rere re lo fini ni okan bale wipe yio jeki ife tubo ma gbile nibi ise itewe Ijesa.

Gbere re o, Omobokun, oju aso funfun kipon olorisa nia, ina eni koma jo ewu lara, Edumare koma jeko ahun ati towo hunu, ase ti Edumare Mo dupe e ku ife ojo o.

Aki- enikan- da- enikan-si baba adaja sile ni.

Mofi iwe yi ki gbogbo awon ore ati arakunrin mi gbogbo nibi ile ise itewe Ijesa.

Enyin enia mi ni mo ki, Abiyamo ki gbo ohun omo re ki o ma lara, Itakun to so igba lo so agbe, on na lo so legede. Ewa e jeki a tun ile baba wa se.

Aikowo rin ejo ni omo araiye fi npa won. Aifohun sokan wa ni awon miran se nfi iwosi lowa, bi a ba ko lukoleu, ao ko jagunnu. E je ka fa ara wa mora, omo owo ki ku loju owo, omo ese k ku loja ese, Ako ni roko fun omo elomiran je.

E je ka fi iwa gbe ile ise itewe Ijesa ga fun ogo wa ati iyi orile ede Ijesa, ise na ti o se fun ise ewe Ijesa koni jasi asan, bi e ba iro wipe awon Omo Obokun to wa ni Ilesa ko mo iyi ise na fun yin, e mase fi eyini ninu, awa omo Obokun to wa ni idale mo yi ise na fun yin, Woli kole ni iyi ni ilu ti a bi, ni oro na je.

E ma boju wo ehin, emi ki san boju wo ehin e ma se ise rere yin na niso, Olorun ore toju ti owo enia yio san ise na fun yin.

Ilesa ogba iyi loju awon enia Abeokuta irohin ko to afojuba, Kabiyesi Adimula Owa alase, ekeji orisa, E ku inawo ojo, Apo na ti e ti mu owo Kabiyesi abudi ma ni tomi, apo na ko ni gbe, efi ife na gba iyi ni ilu Egba, Kabiyesi o, baba wa.

Nipa ti igboro ilu Ilesa, oro na di igba miran, Egan ni ho, eiye bi okin ko si ni igbo ni oro na je fun oju mi.

Ogbeni Momodu ti adugbo Otapete e ku atunse; owo ise na ti e nse lati ona Oke Iyin fan ni ni isiri, o je ohun idunnu pupo ti Ijoka ati Egbedi ko irohin. Idiose te sofun wa wipe kini Eyingbeti nse ti ilu Ilesa ko ni le danwo.

Opo ina kose fi enu so nipa ti ewa, Iyen na to niti wa, Awa lani ijoka titi de idi Ogun iyen na to ewa.

A dupe o, Ijesa.



KANSELỌ ADEGBỌLA BENSON

Ninu iwe wa ose yi, o soro lori bi Wolewo e miran ti se ma nfogbon ba ijoba nipa imototo je. O ni opolopo wolewole ti ibi ise won wa lagbegbe lo njoko si igboro to si ngbowosu lekun.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| **OJU EWE KINI** | | | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |
| **OJU EWE KEJI** | | | |
| igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |
| **OJU EWE KETA** | | | |
| gba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |
| **OJU EWE KẸJỌ** | | | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, ATI 7 JE OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

